# ỌRỌ IYANJU LORI YIYIN ỌLỌRUN

**Orin Dafidi 33:1-22**

**ẸKỌ 31 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ohun rere ni lati ma fi ọpẹ fun OLUWA, ati lati ma kọrin si orukọ rẹ, Ọga-ogo:" (Orin Dafidi 92:1).**

**I Iyin Ọlọrun Jẹ́ Ojuṣe ati Anfaani Wa**

1 Isin ati iyin Ọlọrun jẹ́ anfaani ati ojuṣe fun awọn olododo, Orin Dafidi 33:1

2 Ati pẹlu eyi, a ni lati yin In pẹlu ohun elo orin, Orin Dafidi 33:2; 150:1-6

3 A ni lati kọrin iyin si I pẹlu, Orin Dafidi 33:3; 149:1-9; Efesu 5:19, 20; Kolosse 3:16

**II Awọn Idi Rẹ̀ Fun Wa Lati Yin Ọlọrun Bi a ti fi Hàn Ni Igba ti o ti kọja**

1 A ni lati yin In fun Ọrọ agbara Rẹ̀ ti a fi hàn ni didá aye, Orin Dafidi 33:4, 6, 8, 9; 148:1-6

2 A ni lati yin In fun iṣẹ iyanu ti O ti ṣe fun ire wa, Orin Dafidi 33:4, 6, 7, 9; 148:7-14; Isaiah 12:1-6

3 A ni lati yin In fun otitọ, ododo ati oore Rẹ̀ -- awọn iwà ayebaye ti a fi hàn wá nipa ibalo Rẹ̀ pẹlu awọn ọmọ eniyan, Orin Dafidi 33:4, 5

4 A ni lati yin In fun idajọ ododo Rẹ̀, ti a fi hàn ninu iwa Rẹ̀ si awọn Keferi, Orin Dafidi 33:5, 8, 10; Romu 1:19-21

5 A ni lati yin In fun ailopin ọgbọ́n ati ifẹ Rẹ̀ ti o fara hàn nipa ifẹ inurere Rẹ̀ fun ire gbogbo eniyan, Orin Dafidi 33:4, 8, 10, 11; Romu 11:33-36

**III Diẹ Ninu Awọn Idi Rẹ̀ Ti A fi Ni Lati Maa Yin Ọlọrun Nisisiyii**

1 Oun n ronu nipa awọn wọnni ti o fẹ Ẹ ti o si n bu ọlá fun Un, O si n nawọ ibukun Rẹ̀ si wọn, Orin Dafidi 33:12-15

2 Agbara awọn eniyan ailera lasan ni, Orin Dafidi 33:16, 17; 20:7; 118:8, 9

3 Ifẹ Ọlọrun fara hàn nipa pipese fun aini wa ojoojumọ nipa ti ẹmi ati nipa ti ara, Orin Dafidi 33:18, 19; Luku 12:22-31; Johannu 3:16; Romu 8:38, 39

4 Oore-ọfẹ: Igbẹkẹle wa patapata ninu Ọlọrun, Orin Dafidi 33:20-22; Juda 24, 25

## ALAYE

Ẹsẹ akọsori wa sọ wi pe "ohun rere ni lati ma fi ọpẹ fun Oluwa, ati lati ma kọrin" si orukọ Rẹ Ọga ogo. Ọrọ Ẹkọ wa paṣẹ fun gbogbo Onigbagbọ́ lati yọ̀ ninu Oluwa ati lati maa yin In ni gbogbo ọ̀na. Bayii ni a ri i ninu awọn ọrọ wọnyii, pe iyin yii kò gbọdọ jẹ́ ohun ti a le ṣe nigba ti o ba wù wá, tabi lọna ti o ba wù wa, ṣugbọn o ni lati jẹ́ iṣẹ wa lojoojumọ, dajudaju o jẹ pataki apa kan iṣẹ́ isin wa si Ọlọrun.

A kọ Psalmu iyanu yii ni ọna ti o le yé ni, o si ṣe alaye ni kikún, ẹ̀kọ́ lori iyin daradara, to bẹẹ gẹẹ ti a kò tun fẹ alaye pupọ lati mu ni mọ̀ titobi ati adun rẹ̀. Ẹmi Mimọ́ n fi ye ni lati ẹnu Onpsalmu pe iyin si Ọlọrun ki i ṣe anfaani fun Onigbagbọ nikan, ṣugbọn ojuṣe rẹ̀ ni pẹlu, niwọn bi Ọlọrun tikara Rẹ̀ ti pa a laṣẹ. Kristi wá lati fi ẹmi iyin sinu ọkàn wa, nitori a ka a ninu Isaiah 61:3 pe, ọ̀kan ninu iṣẹ ti o wá ṣe ni aye ni lati fi "ọṣọ́ fun wọn nipo ẽrú, ororo ayọ̀ nipo ọ̀fọ, aṣọ iyìn nipo ẹmi ibanujẹ" ki a baa le pe wa ni "igi ododo."

A ri i ninu ẹkọ wa lati inu ohun-ọ̀ṣọ́ iyebiye ninu iwe-iṣura ti Orin Dafidi pe, a ni lati yin Ọlọrun lọna gbogbo ti eniyan ba mọ̀. Nibo miiran Bibeli sọ fun ni pe ohun gbogbo ti a dá ni o n yin In, ati pe oorun, oṣupa, awọn irawọ ati awọn ọrun paapaa n yin, wọn si n sin Ẹlẹda wọn. Bibeli bẹrẹ pẹlu ohun ti a le pe ni "Orin Iṣẹda Ayé," Jobu si sọ nipa ti awọn irawọ owurọ ti wọn jumọ n kọrin pọ̀ nigba didá ayé. A le kà ninu Iwe Ifihan pẹlu ti o n sọ nipa ti awọn ẹgbẹ́ akọrin ọkẹ aimoye ti n kọrin yí Itẹ Ọlọrun ká. Olukuluku eniyan ni yoo kọrin ni Ọrun!

Ṣugbọn kò ṣẹṣẹ di igba ti a ba de Ọrun ki a to gbadun iriri ologo yii. Lati ipilẹṣẹ ni a ti kọ Psalmu fun orin kikọ, paapaa adùn wa ninu itumọ wọn ti o ju awọn iwe miiran lọ. Mose kọ́ awọn Ọmọ Israẹli lati kọrin; Debora, ọ̀kan ninu awọn onidajọ wọn fi orin iṣẹgun ti kò le kú yin Ọlọrun logo. Dafidi jẹ́ olorin ti o gbamuṣe, nitori o kọrin pẹlu ohun-elo orin ni agbala ọba, a si gbọ́ pe o kọrin iyin si Ọlọrun pẹlu gbogbo ọkàn rẹ̀.

Ni igba laelae, bi a ti kọ́ọ́ ninu Bibeli, ọpọlọpọ ohun-elo orin ni wọn ni ti a ko ṣe dara to tiwa lonii, ṣugbọn ti o le fun ni ni orin ti o dùn pupọ. Orişirişi ohun elo orin olokun ati fere ni o wà, ninu wọn ni harpu, psalteri, fere, fere alapa, iwo ati ipè; pẹlu awọn wọnni, wọn ni ilù, timbreli ati kimbali, awọn wọnyii jẹ́ ohun-elo orin ti a ṣe fun títa tabi lilù. Gbogbo wọnyii ni Dafidi Onipsalmu lò ninu ẹgbẹ akọrin rẹ̀, ti a sọ fun wa pe o to ẹgbaaji (4,000) ki o baa le maa fi kọrin iyin alarinrin si Oluwa (1 Kronika 23:5).

Jesu maa n sọ ọrọ inu Psalmu pupọ, o si maa n tọka si wọn nigba pupọ, o si wi pe pupọ ohun ti a kọ sinu wọn jẹ́ nipa Oun. Awọn Psalmu wọnni ti o sọ pato nipa wiwá Kristi si ayé ni a n pe ni Psalmu nipa Messia. Jesu ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ kọ orin kan lẹyin ti wọn ti jẹ ounjẹ Alẹ Oluwa tán, ki wọn to lọ sinu ọgbà nibi ti a o gbé ti fi Jesu hàn. Ọrọ ikẹyin Rẹ̀ paapaa, nigba ti o wà lori agbelebu, jẹ ọ̀rọ lati inu awọn iwe iyanu wọnyii wá.

Lẹyin ti Jesu ti goke lọ, a ri i pe ijọ si n yin Ọlọrun sibẹ ni ọ̀na bayii. Awọn Onigbagbọ́ igbaa nì ninu aşikiri ibi isin wọn – nigba pupọ ninu ihò ati ihò inu apata ti wọn fi ara pamọ́ si kuro lọwọ awọn ti ki i ṣe Onigbagbọ́ nitori inunibini ti o gbona ni ọjọ wọnni – n fi orin ati ọ̀rọ sisọ lẹnu yin Ọlọrun logo. Paulu Apọsteli sọ ninu awọn iwe rẹ̀ fun ijọ igba nì -- ati fun awa naa pẹlu – pe gbogbo Onigbagbọ́ ni lati maa bá ara wọn sọ̀rọ ninu iyin Ọlọrun nipa “psalmu, ati orin iyìn, ati orin ẹmí.” Lẹyin naa bi isin Ọlọrun ti n gbilẹ kaakiri agbaye, ati bẹẹ lọ la Igba okunkun já -- pẹlu iṣina ati okunkun nipa ti ẹmi ti ọjọ wọnni -- awọn Onigbagbọ́ ti fi awọn orin ti n tu ni ninu wọnyii sọ igbagbọ́ ati ifẹ wọn di ọ̀tun.

“Ohun rere ni lati ma fi ọpẹ fun OLUWA, ati lati ma kọrin si orukọ rẹ, Ọga ogo.” Ẹ má ṣe jẹ ki a gbagbe ọ̀rọ iyanju ẹsẹ ọrọ yii, tabi ọ̀rọ iyebiye ori ẹ̀kọ́ wa yii ti o rú ifẹ wa soke, eyi ti a kọ lati fi ọ̀na igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun ninu ayé hàn wa, ati imurasilẹ fun Ọrun, nibi ti a o lo ayeraye ni sisin ati ni yiyin Ẹni ti O fi Ẹjẹ Rẹ̀ rà wa, ti O si rà wa pada kuro lọwọ ọta nì.

**AWỌN IBEERE**

1 Njẹ o jẹ́ ọranyàn fun wa lati yin Ọlọrun?

2 Ọna wo ni awọn Onigbagbọ́ igbaanì n gbà yin Ọlọrun?

3 Ki ni idi pataki ti a fi kọ awọn Psalmu lati ipilẹṣẹ?

4 Nitori ki ni a ṣe ni lati yin Ọlọrun?

5 Bi a ba jẹ olooto̩ ninu iyin wa si Ọlọrun, ki ni a le reti lẹyin naa?

6 Ta ni kọ pupọ ninu Psalmu wọnyii?

7 Ki ni “orin” kin-in-ni ninu Bibeli?

8 Awọn eniyan meloo ni yoo wà ninu ẹgbẹ́ akọrin ti yoo maa kọrin yika Itẹ Ọlọrun?

9 Orukọ wo ni a fun Psalmu ti o sọ asọtẹlẹ nipa Jesu?

10 Bawo ni a ṣe le yin Ọlọrun?